# IRỌPO ẸNI: JESU JIYA DIPO ẸLẸṢẸ

**Filemoni 1 - 25**

**ẸKỌ 354 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ẹ mã ṣore fun ọmọnikeji nyin, ẹ ni iyọ́nu, ẹ mã dariji ara nyin, gẹgẹ bi Ọlọrun ninu Kristi ti dariji nyin" (Efesu 4:32).**

**I Ipadabọ̀ Onesimu**

1 Iyipada ọkàn Onesimu, iranṣẹ Filemoni ti ọna rẹ̀ buru nigba kan ri, ni o mú ki Paulu kọwe si Filemoni, Filemoni 1-12

2 Paulu fẹ gba Onesimu sọdọ ara rẹ̀, ṣugbọn o tun ro ti ẹtọ ti Filemoni ọga rẹ̀ ni, lati maa lo o gẹgẹ bi iranṣẹ rẹ̀, Filemoni 13, 14

3 Paulu gba Filemoni ni imọran pe, bi o tilẹ jẹ pe Onesimu gẹgẹ bi iranṣẹ ti salọ fun igba diẹ, o n pada bọ̀ sọdọ rẹ̀ gẹgẹ bi arakunrin ninu Oluwa, eyi ki i ṣe fun igba diẹ, ṣugbọn titi lai, Filemoni 15, 16; Titu 2:9, 10; Efesu 6::5-9

4 A sọ fun Filemoni lati gba Onesimu gẹgẹ bi i ba ti gba Paulu tikararẹ, Filemoni 17; Matteu 10:40-42; 12:48-50; 25:40

5 Paulu fẹ ki Filemoni ka gbogbo gbese Onesimu si oun lọrùn, nipa bẹẹ o n fi apẹẹrẹẹkọ nla ti Ihinrere hàn ninu eyi ti Kristi ru gbogbo aṣiṣe wa ti O si n bẹ Ọlọrun sibẹ pe ki O dariji wa nitori ti Rẹ̀, Filemoni 18, 19; Isaiah 53:5, 12; Romu 3:24; 4:25; 5:1-21; 2 Kọrinti 5:18, 19; Efesu 2:13; Kolosse 1:14; 1 Johannu 4:10

6 Paulu ni idaniloju pe Filemoni yoo fi tayọtayọ gba Onesimu, Filemoni 19-25

## ALAYE

**Iyipada Onesimu**

A le fi Episteli Paulu si Filemoni ṣe akawe itàn ọmọ oninakuna nipa pe o jẹ akopọ gbogbo itan Ihinrere. Ironupiwada, igbala, atunṣe, ẹbọ irọpo fun ẹṣẹ gbogbo eniyan ti Kristi fi ara Rẹ̀ rú, ati idariji Ọlọrun – gbogbo nnkan wọnyii ni a le ri ninu itan ẹrú ti o yi pada yii.

Koko ọ̀rọ ti o wa ninu Episteli yii si Filemoni ni nipa ẹru kan ti a n pà ni Onesimu. Itumọ orukọ rẹ̀ ni "Li ere," ṣugbọn o ti fi ara rẹ̀ hàn bi alailere fun oluwa rẹ̀, Filemoni. O ti hu iwa buburu pupọ, lẹyin naa o fi oluwa rẹ̀ ati iṣẹ rẹ̀ silẹ, o si salọ. Ni Romu, Onesimu bá Paulu Apọsteli pade. A gbagbọ́ pẹlu ẹri ti o fidimulẹ pe a mú Onesimu ni Romu gẹgẹ bi ẹrú ti o sá, a fi i sinu iṣẹ ọmọ-ogun Romu, ati pe iṣẹ́ ti a yàn fun un ni lati maa ṣọ́ Paulu. Lọna iyanu Ọlọrun, bi Onesimu ti n salọ kuro ni ile ati kuro nidi iṣẹ ọga rẹ̀ Onigbagbọ́, o ba ara rẹ pada ni didè pẹlu Paulu.

Bi o tilẹ jẹ pe Onesimu dabi ọmọ buburu fun ọga rẹ Filemoni, sibẹ ayà kò fo Paulu nipa akọsilẹ rẹ̀ atẹyinwa. Paulu le bojuwo igbesi-ayé ara rẹ̀ atẹyinwa, iwa rẹ̀ ati bi ọkan rẹ ti ri nipa Kristi. Bi o tilẹ jẹ pe Paulu ki i ṣe arufin ni ọna ti Onesimu fi gbà jẹ arufin, Paulu paapaa ti huwa buburu si Ihinrere to bẹẹ ti o fi pe ara rẹ̀ ni pataki ninu awọn ẹlẹṣẹ. Siwaju si i, Paulu sọ pe; "Ṣugbọn nitori eyi ni mo ṣe ri ãnu gbà, pe lara mi bi olori, ni ki Jesu Kristi fi gbogbo ipamọra rẹ̀ hàn bi apẹrẹ fun awọn ti yio gbà a gbọ si iye ainipẹkun nigba ikẹhin" (1 Timoteu 1:16).

Nitori ibalo timọ́timọ́ ti Onesimu ni pẹlu Paulu, lai pẹ lọ titi o yipada di Onigbagbọ́ tootọ, a si tun un bi si Ijọba Ọlọrun.

**Ẹda Titun ninu Kristi Jesu**

Wolii Jeremiah beere ibeere yii nigba kan: "Ara Etiopia le yi àwọ rẹ̀ pada, tabi ẹkùn le yi ilà ara rẹ̀ pada? bẽni ẹnyin pẹlu iba le ṣe rere, ẹnyin ti a kọ́ ni ìwa buburu?" (Jeremiah 13:23). Irú ipò iṣoro bayii gan an ni Onesimu wà, bakan naa ni o ri fun olukuluku ọkan ti a ko i ti i yipada ki a si sọ ọ di ọ̀tun. Onesimu kò le yi ifẹ rẹ̀ si iwà ibi pada, a kò tilẹ mọ̀ boya o ni ifẹ ati yipada rara. Ṣugbọn Ọlọrun ninu aanu Rẹ̀ ṣe amọna rẹ si ọdọ ẹni kan ti o le sọ ẹri ọkàn rẹ̀ ti o ti kú ji, ki o si fun un ni ipinnu lati jẹ́ eniyan ọ̀tọ dipo ọdaran. Nigba ti ifẹ lati ṣe rere ba dide ninu ọkan eniyan, Ọlọrun yoo fun un ni agbara lati di alaaye ati lati jẹ́ olododo dipo ki o jẹ okú ati ẹni idalẹbi titi ayeraye. Iwe mimọ́ sọ pe: "Ṣugbọn iye awọn ti o gbà a, awọn li o fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun, ani awọn na ti o gbà orukọ rẹ̀ gbọ́: awọn ẹniti a bi, ki iṣe nipa ti ẹ̀jẹ, tabi nipa ti ifẹ ara, bẽni ki iṣe nipa ifẹ ti enia, bikoṣe nipa ifẹ ti Ọlọrun" (Johannu 1:12, 13).

Gbogbo iwa rere ti kò si ninu Onesimu tẹlẹ ni o bẹrẹ si hàn ninu iṣe rẹ lẹsẹkẹsẹ ti o ni iyipada ọkàn. Alaiṣeefi-ọkan tán ni tẹlẹ, alaiṣootọ ninu iṣẹ́ rẹ, olè ati isansa nitori iwà ibi rẹ. Lẹyin iyipada ọkan rẹ, o wá yatọ patapata: o di oloootọ, alaiṣeru, oloootọ iranṣẹ ninu ipe Kristi, ati apẹẹrẹ Onigbagbọ rere. Lakoko yii Paulu jẹ́ onde ijọba Romu, kò si ni anfaani kankan. Onesimu ṣọwọn fun Paulu lati pinya pẹlu rẹ̀ nigba ti Onesimu pinnu lati pada sọdọ ọga rẹ̀ atijọ.

**Atunṣe**

"Ọlọrun si bère eyi ti o ti kọja lọ" (Oniwasu 3:15). Lai pẹ titi o bẹrẹ si wá sọkàn Onesimu lati pada si ọdọ Filemoni oluwa rẹ̀ lati ṣe atunṣe gbogbo buburu atẹyinwa. Ọfẹ ni Ọlọrun maa n fi ẹ̀ṣẹ awọn eniyan ji, ṣugbọn Oun kò gba ẹnikẹni laayè lati maa lọ lai jẹwọ gbogbo iwa buburu ti o ti hù bi o ba ṣe e ṣe ati lai mu gbogbo ohun ti o ti wọ́ pada bọ si titọ. Ifẹ lati ṣe atunṣe igbesi-ayé ti a ti lò ni ilokulo jẹ́ ami riri igbala tootọ. Ofin pa a laṣẹ pe a ni lati ṣe atunṣe gbogbo aṣiṣe atẹyinwa, a ni lati san oju owo ki a si fi idamarun-un rẹ̀ le e (Wo Lefitiku 6:2-5).

Nigba ti Sakeu, alaiṣootọ agbowo-ode nì yipada, o ṣe ileri fun Jesu lẹsẹkẹsẹ lati ṣe atunṣe. O wi pe: "Wo o Oluwa, àbọ ohun ini mi ni mo fifun talakà; bi mo ba si fi ẹ̀sun eke gbà ohun kan lọwọ ẹnikẹni, mo san a pada ni ilọpo mẹrin" (Luku 19:8).

Aanu Ọlọrun lati ipasẹ Ihinrere n kilọ fun gbogbo eniyan pe ki wọn mu anfaani ironupiwada ati idariji ẹṣẹ wọn nipasẹ ikú ati ajinde Kristi lò. Ọrọ Ọlọrun kilọ pe: "Ẹṣẹ awọn ẹlomiran a mã hàn gbangba, a mã lọ ṣãju si idajọ; ti awọn ẹlomiran pẹlu a si mã tẹle wọn" (1 Timoteu 5:24). Ifẹ Ọlọrun ni pe nipa agbára Ẹjẹ Jesu Kristi, ki ẹ̀ṣẹ gbogbo eniyan hàn gbangba ṣiwaju. Eyi ni pe, ki wọ̀n mọ ẹ̀ṣẹ wọn lẹṣẹ, ki wọn si jẹwọ wọn fun Ọlọrun, ki Ọlọrun ba le dariji wọn. Bi ẹ̀ṣẹ wa ba tọ wa lẹyin kuro ni ayé yii, nigba naa a o jẹ ẹlẹbi niwaju Itẹ Idajọ Ọlọrun; ṣugbọn ki yoo si idariji naa gba naa, bẹẹ ni ki yoo si aanu ti yoo dawọ idajọ ododo Ọlọrun duro lori gbogbo ẹlẹṣẹ ti o kọ Ẹjẹ Kristi silẹ.

Ọlọrun fẹ ki a ṣe atunṣe awọn aṣiṣe wa atẹyinwa laye yii bi a o ba ni ireti lati pade Rẹ̀ ni alaafia nigbooṣe. Kikuna tabi kikọ lati ṣe atunṣe nigba ti o ṣe e ṣe yoo mu ki a yọ wa kuro ninu Ijọba Ọlọrun, yoo si mu idajọ wa daju. Nigba ti igbala Ọlọrun ba wọ inu ọkan kan, lẹsẹkẹsẹ ifẹ kan lati ọdọ Ọlọrun yoo mu ki ọkàn naa fẹ lati lọ ṣe atunṣe. Onesimu n fi ẹwà oore-ọfẹ igbala rẹ̀ hàn nigba ti o ni ọkàn lati pada sọdọ ọga rẹ̀ atijọ lati dojukọ iwa buburu rẹ̀ atẹyinwa. Oun ki yoo tun sá nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀ mọ́, nitori wọn ti kọja lọ a ki yoo si tun ranti wọn si i mọ́.

Bi o tilẹ jẹ pe Paulu n fẹ ibalo Onesimu ati iranwọ rẹ̀ lọpọlọpọ ninu iṣẹ Oluwa, sibẹ o rán Onesimu pada sọdọ Filemoni pẹlu ọ̀pọ adura. Iwe rẹ̀ si Filemoni jẹ́ iwe ti o dara lọpọlọpọ ti o si kún fun ẹ̀bẹ ti o mu ni lọkan pe ki Filemoni le gba ẹrú rẹ̀, Onesimu pada, ẹni ti o ti jẹ́ alailere ni saa kan ri, ṣugbọn ti o wulo pupọ nisisiyii. O ti salọ gẹgẹ bi ẹrú, ṣugbọn o n pada bi iranṣẹ ati arakunrin ninu Oluwa. Paulu daba pe boya Onesimu fi igba kan lọ ki Filemoni ba le ni in lọdọ titi. Labẹ Ofin Majẹmu Lailai lẹyin ti ọmọ-ọdọ bá ti sinru fun saa kan, ọga rẹ̀ gbọdọ jẹ ki o maa lọ. Bi o ba si fẹ lati maa sin ọga rẹ si i, ọga rẹ̀ yoo lu iho si i leti. Iho eti rẹ̀ ni yoo jẹ́ ami fun ẹnikẹni ti o ba ri i ki o le mọ pe oun tikara rẹ̀ ni o yàn lati maa sin oluwa rẹ̀ titi ayé. (Ka Ẹksodu 21:1-6; Orin Dafidi 40:6). Onesimu yàn ni tootọ lati pada sọdọ oluwa rẹ̀ atijọ ki o ba le fi ifẹ ọkàn ati àya rẹ̀ sin in gẹgẹ bi si Oluwa. Ki i tun ṣe isin ti ẹrú ti ó wà ninu idè, ṣugbọn isin ati iṣẹ́ ti ifẹ.

**Kà a Si Mi Lọrùn**

Iwe ti Paulu kọ si Filemoni pe ki o gba Onesimu pẹlu iyọnusi kọja bibẹbẹ lasan fun aanu ati idariji. Pẹlu awọn gbolohun ọ̀rọ ṣokiṣoki diẹ, Paulu fi kókó Ihinrere Jesu Kristi hàn ni ọ̀na ti o dara. A ti sọ Filemoni di Onigbagbọ nipa iwaasu Paulu, ṣugbọn Paulu kò beere pe ki Filemoni dariji Onesimu nitori pe wọn jẹ́ ọrẹ. Awọn ọrọ Filemoni leti Ẹni kan ti O san gbese rẹ̀, ti Filemoni paapaa fi bọ́ lọwọ ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ati pe ki oun naa dariji Onesimu gẹgẹ bi Kristi ti dariji oun naa. (Wo Matteu 18:23-35).

Ọrọ Paulu, "Nitorina bi iwọ ba kà mi si ẹlẹgbẹ rẹ, gbà a bi emi tikarami. Ṣugbọn bi o ba ti ṣẹ̀ ọ rara, tabi ti o jẹ ọ nigbese kan, kà a si mi lọrun," wá nipa imisi Ẹmi Mimọ́; o si ṣe apejuwe ni iwọn iba ọ̀rọ diẹ, ohun ti ẹbọ irapadà Jesu Kristi jasi, eyi ti o tó fun ẹ̀ṣẹ gbogbo ẹda. Ẹlẹṣẹ, ti a wẹ̀ mọ́ kuro ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀, le pada si ile Oluwa rẹ̀, ki o si mú ihin ilaja ti o ri gbà lọdọ Kristi lọwọ. Jesu Kristi kò ha wi fun Baba Rẹ̀ nitori ẹlẹṣẹ-kẹlẹṣẹ ani gbogbo ẹlẹṣẹ ti yoo ba rọ̀ mọ́ Ẹjẹ Kristi fun idalare wọn pe "Gbà a bi emi tikarami"? "Nitorina bi iwọ ba kà mi si ẹlẹgbẹ rẹ, gbà a bi emi tikarami. Bi o ba ti ṣẹ̀ ọ rara, tabi ti o jẹ ọ nigbese kan, kà a si mi lọrun." Nipa agbára Ẹjẹ Jesu Kristi, Ọlọrun n gba ẹlẹṣẹ ti o ba ronupiwada gẹgẹ bi O ti gba Ọmọ Oun tikara Rẹ̀, ani Jesu Kristi! Ẹtọ ti Jesu Kristi ní ni a n wò mọ́ ẹlẹṣẹ lara; aitọ́ ati abuku ti ẹlẹṣẹ ní ni Jesu Kristi ti san gbese rẹ̀ ti O si ti ṣe etutu fun.

Bi o ba “jẹ ọ nigbese kan” -- ẹlẹṣẹ wo ni kò jẹ Ọlọrun ni gbese ti o pọ̀ to bẹẹ ti kò fi le san án? Ta ni kò ti i dẹṣẹ ki o si kunà ogo Ọlọrun? Sibẹ lai ka ibi ti ẹnikẹni ti ṣe si ijọba Ọlọrun si, Jesu wi pe Oun yoo fi ara Oun dipo wọn lati bẹbẹ fun wọn niwaju Baba Rẹ̀. Jesu Kristi le gba ẹjọẹlẹṣẹ ti o ronupiwada wi ni awijare nitori pe O ti gba iya gbogbo ẹlẹṣẹ jẹ. “O si rù ẹ̀ṣẹ ọ̀pọlọpọ; o si n ṣipẹ̀ fun awọn alarekọja” (Isaiah 53:12). Oun ni Ọdọ-agutan Ọlọrun -- Ọdọ-agutan ti kò ni aleebu tabi abuku – ti a ti pa lati ipilẹṣẹ ayé; ati nitori Ẹbọ arukún ati arudà yii Ọlọrun a maa fi ododo fun awọn wọnni ti o ba gbagbọ́ pe Ẹjẹ Kristi ti a ta silẹ tó fun idariji ẹ̀ṣẹ.

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni itumọ Onesimu?

2 Ki ni ṣe ti Onesimu fi kuro nidi iṣẹ ọga rẹ̀?

3 Ṣe alaye bi Onesimu ṣe ni iyipada ọkàn?

4 Ki ni ṣe ti Onesimu fi fẹ́ pada sọdọ ọga rẹ̀ atijọ?

5 Irú ipò wo ni Onesimu wà nigba ti o pada sọdọ Filemoni?

6 Ki ni ṣe ti Paulu fi sọ fun Filemoni pe ki o gba Onesimu gẹgẹ bi yoo ṣe gba oun Paulu?

7 Fun awọn wo ni Jesu yoo sọ fun Baba Rẹ̀ pe “Gbà a bi emi tikarami”?

8 Ọna wo ni a gbà ka ẹ̀ṣẹ awọn eniyan si Jesu Kristi lọrùn?

9 Ki ni itumọ agbára ti n bẹ ninu Ẹjẹ Jesu Kristi?

10 Ki ni ṣe ti Ọlorun ki yoo fi gba awọn ẹlẹṣẹ bi kò ṣe pe wọn ba gba ọ̀na Ẹjẹ Jesu Kristi?

11 Ki ni ṣe ti atunṣe fi ṣe pataki?